**Lakaye Oro**

Bi Olorun ba se o ni Ologa, r o r a ma jaiye. Bi ara-ye ba gbe o ka ori Esiu, Mase jeki ijanu re ja mo o lowo.

Se pelepele, eniti o ba fi oju di aiye aiye yio yi iwaju re sipako. Oluware pari aiye re auni.

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

**Owe**

Eniti ko to gelete to mi fin. Gidigidi ko mole, ka sese fi eru ko da nkankan. Iya ni W u r a, Baba ni Jigi. Bi iya nla ba gbe ni sonle, kekere agon ori eni. Orisa bi i y a ko si. Egbe eni la n g u n Iyan Ewura pe.

VOL. V No. 302 MONDAY SEPTEMBER 25 — OCTOBER 1 1961 KOBO MEJI (2d)

# Awon Okolokoji meji Jijakadi fun odun mefa nitori Omo kan

**ABEOKUTA:— A GBO IROHIN WIPE AWON OKOLOKOJI MEJI BA ARA WON FA I J O G B O N LORI WIPE IWO KO LO NI OMO YI, T E M I NI, FUN ODIDI ODUN MEFA GBAKO, KI BABA EGBE OLOYE SOETAN TO WA FI OPIN SI EDEKOYEDE NA TI O TI NJA RANYIN NILE LATI OJO YI WA. OGBENI GANIYU AYINDE LO GBE EJO SI KOTU PE, IYAWO ON TO NJE SINBIATU FI OYUN OSU MEFA SINU NI GBATI O FI KO ON SILE.**

Ti o si lo bimo na sile odo Rafiyu Akanbi oruko omo ti nwon nja le lori na ni Aliakimu Adisa, nitorina ki adajo ba on gba omo na lowo Rafiyu. Rafiyu Akanbi taku wipe rara, omo na ko nse ti Ganiyu nitoripe, Iya omo na ko ni muradi kan papo pelu Ganiyu Kini omo na fi jo o, ki adajo wo o?.

Sinbiatu iya omo na rojo fun adajo wipe, Iyawo Rafiyu ni on ti nse ri, ki on to wa ko jade k u r o ninu ile re, lehin na ni oro ile wa pa on pelu Ganiyu po, nigbati on si ma bi omo na, on ko bi sinu ile G a n i y u tabi ti Rafiyu. Abudu Ganiyu Alapata, okolokoji re Abudu Rafiyu je Brikila.

Edekoyede yi wa nile lati o d u n 1956, Adajo so wipe, ki Abudu Ganiyu Alapata, ma fi owo mu omo na, sugbon ki Rafiyu ma se san owo irin ese rara.

## Ofo nla se egbe Majeobaje (U. N.) ti gbogbo aiye

Agbo ju igba nu ni ti Ogbeni kan ti ise akowe egbe Majeobaje ti gbogbo aiye, eniti oruko re nje Dag Hammarskjoeld wipe o ku sinu oko ofurufu kan ti o nfo lo si Ilu Katanga lati lo pade Tshombe fun ajoso oro, ti oko na si ja lule nigbati o rin to iwon buso meje si ilu kan ti nwon npe ni Ndola.

Ninu awon enia mefa ti nwon ku sinu oko ofurufu na, ni agbe ri oku akowe egbe na Okunrin kan tio nsun edu lokoko mu irohin wa, ki nwon to ran oko ofurufu kan lo lati lo wo ibe. Enia mejila ni emi re rasu sinu jamba na.

Ero mesan, ati awon osise marun lombe ninu oko ti jamba sele si na enikan soso ni a sese ri ti o yege ninu awon ero oko ni. Oko ofurufu ti ijoba Rhodesia ti bere sise iwadi nipa ohun ti o fa sababi jamba. Nitoripe Iromi ko njo l-sin, bi ko ba si ohun o . u . u f un Iromi labe omi.

Akowe egbe Majeobaje na nlo pade Ogbeni Tshombe lati ni muradi oro alafia papo ni jamba yi sele. Ijoba ile Amerika ti fi iwe sodepe awon gbagbo pe Iku ti o pa Dag, je jamba lati owo omo enia Eni keni ki o bale fun awon irohin bi jamba na tise sele yio gba ebun egba mejo. (17,000.)

## Olopa fi esun Obinrin kan sun pe, on lopa omo re

**London:— Obinrin adelebo kan ara Ile Naijiria** ti o ngbe ilu Oyinbo, ni a awon Olopa fi sun esun wipe on lo pa omo re okunrin ti o njo Joseph, omo odun mefa. Bi a ti gbo oro na si niyi wipe, obinrin adelebo na ti o nje Vipleta Osuagu lu omo re ni ilu alailanu tobe ti o da ogbe si lara, asehinwa asehinbo, omo na si ile Olorun wo, o si ku. Nse ni awon Olopa taku woale ti obinrin na lorun ki Adajo to wa ye Igbejo na si ose ti o mbo.

## Awon Ijoye Ibile Eko yan eniti yio je oye Eletu Odibo



**EKO:-** Eniti a gbo wipe nwon yan si ori oye Eletu Odibo, ti yio ropo Ologbe Amusa Gbadesere ni Ogbeni I. O. Bajulaiye, ti nse Oluko agba nibiti a gbe nko awon omode ni Eko.

Awon Ebi Eletu Odibo nse ipalemo lowolowo nisisiyi lati mu oloye titun yi lo han Alaiyeluwa Oba Adele Keji ninu Iga Idunganran ati lati fi han awon Oloye Onifila funfun. Ogbeni Bajulaiye ni a nwo ninu aworan yi, ti nwon nfi Fila Oye de e lori.

# SE BOTIMO APA 3

LATI QWQ:- FUNMILAYO KOFOWOROLA

Bi awọn mejeji ti yọ si ọna gboro na, ni nwọn ba pade Baba Arugbo kan ti o nha rigorigo loju ọna, ẹru ba wọn gidigidi nitoripe Alujanu ni wọn npe, nwọn ki titi, ko da wọn lohun, nṣe lo dorikodo nigbati o ya ni Ṣebotimo sunmọ, o ni Alagba, a ki ọ titi, o ko da wa lohun, ṣe ko si nkankan o.?

ARUGBO NA GBORI SOKE.

Ki Ṣebotimọ to wi bayi tan, Arugbo na gbe ori soke, o si ṣiju wo wọn pẹ e, o ni alafia fun nyin ẹnyin ọmọ de wọnyi, awọn m e j e j i si da lohun pe Aro o, Baba ogbo, a tọ o. Oju ti o si wo wọn ba wọn lẹru pupọ, ti olukuluku wọn fi dojubolẹ, gbogbo a r a wọn si ti ku tuitui bi iṣu ti o ran, nigbati Arugbo na ri wipe ẹru ba wọn, o ni ẹ ma ṣe beru, bẹni ki ẹ ma ṣe ṣ'ojo, IRAN-LOWỌ ni orukọ mi, ẹ tẹti silẹ ki ẹ gbọ.

Odua ti fi mi sihin lati ọdun jọjọ lati ma ran awọn enia ti o ba nilẹ Iranlọwọ lọwọ, ọjọ ori mi pẹlu Ilẹ ni o dọgba' nitorina ki o ma ṣe jẹ Iyalẹnu fun nyin pe, nko ri bi enia ti nri, Ogbo lo sọ mi da bẹ ẹ. Ki nma fi ọrọ da nyin duro lọ titi, ẹ ṣiju soke ki ẹ wo mi, nitoripe oju ni ọrọ wa, bi awọn mejeji si ti ṣiju s'oke, ni Baba Arugbo ti wọn ti ri lakọkọ ba di ọdọmọkunrin ti ehin pe si lẹnu ṣaṣiṣa, o si bẹrẹ si rerin si wọn, o ni alafia fun yin, wọn si da lohun pe, ati fun on na.

EDAKUN KINI E WA DEHIN O?

Eru ya Sebotimọ to bẹ ge, ti o fi bere lọwọ rẹ pe, Alagba nje ẹnyin ha kọ ni Arugbo a kọkọ ti o nba wa sọrọ bi? o si da lohun pe Iwọ wi, awọn mejeji wa feti ko ara wọn leti, ni Ṣebotimọ ba sọ fun ekeji rẹ pe laiṣe ani ani, Igbo alujannu ni awọn wa.

IRANLOWO TUN BERE ORO LOWO WON

O tun bere lẹkeji, o ni a ni kini ẹ wa de ihin? Ṣebotimọ wa da lohun bayi pe, a nwa owo lọ ni, wọn ti da ọjọ ti a ma gbe Iyawo s'ona, ṣugbọn kò si owo Idana ni a ba fi gba ọdọ Babalawo lọ, ana ti o ni a o gba fi ri owo ni a si tẹle yi, bi o ti jẹ ni yẹn o Alagba. Iranlọwọ rerin ke! ke! ke! o ni owo tabi kinla? wọn ni bẹ ẹ ni, o ni njẹ e mọ ẹniti kọkọrọ owo wa lọwọ rẹ? Nwọn ni awọn ko mọ, o ni ti wọn ko ba mọ, o ni Eṣu ni.

NJE ENYIN HA LE TELE EṢU?

Iranlọwọ wa bere lọwọ wọn pe, njẹ wọn ha le tẹle eṣu, ki nwọn si ma a sin, nitoripe ẹniti o ba nwa owo ni lati jẹ ọmọ ẹhin eṣu, ki o si ma tẹle ilana rẹ, ẹ ronu nyin dada ki ẹ to fun mi lesi o.

Awọn mejeji bẹrẹsi wo ara wọn loju, ni Iranlọwọ ba ni ẹ ro dada ki nto pada de lọla o. Bi idan ni o ba poora mọ wọn loju, ọna na ni wọn sun si di ọjọ keji.
AKIYESI: Iyoku di ọsẹ to mbọ lagbara Ọlọrun o.

## Oloye Akintola ati Opara jumo nfe Alafia fun ile Naijiria

KADUNA:- Orin awọn Babalawo kan ti o fẹrẹ fi ara jọ ọrọ ti a fọ sọ yi ni o kọ bayi wipe:- Olukọtun ati Ajaguna, Oloye meji lo rira wọn.

Oloye S. L. Akintọla ati Dr. Ọpara, awọn mejeji nwọn yi ti mba ara wọn fa kokowa lọna ti iṣelu tobẹ ti ọrọ na fẹrẹ di ogun ati ọtẹ.



Agbalagba ko nsa wa ni ọja ko ri ọmọ titun wo, awọn Ọjọgbọn pe awọn alagbara mejeji nwọnyi papọ si ilu Kaduna nilẹ Hausa, nwọn si pẹtu si nwọn ninu.

Awọn alagbara mejeji na si fi tọkan tọkan ṣe ipinnu bayi wipe, awa aṣiwaju mejeji ti a ti ntako ara wa latẹhin wa, fi ori ko ori, a si fi inu lu inu papọ a ri wipe alafia lo le mu iṣọkan ba ilẹ wa, a fi mọ ṣọkan wipe a ko ni gba ki ẹnikẹni ma da ọwọ ọbẹ tẹlẹ nipa fifi agbara rẹ ṣe ohunkohun ti o wu, ki o si ma da ofin kọja.

Ki a ma wa ire awọn Ọmọ Iya wa, a ko si fẹ wipe, emi ni Hausa, Iwọ ni Ibo, on ni Yoruba ki a ma wa ire ara wa ati lọsiwaju ilẹ Naijiria, ki a si fi ara wa ṣọkan. A fi eyiyi kesi gbogbo awọn ẹgbẹ Alakukọ, Ọlọpẹ Olomi, Ọlọkọ, ati Onigbalẹ ati Dẹmọ, ki onikaluku sa agbara rẹ lati pa ofin pẹlu aṣẹ mọ larin gbogbo enia.

Nitoripe ki awọn Ọlọpa oke ọya, pẹlu Ọlọpa Ibilẹ wa ni abẹ awọn Ọlọpa Ijọba iyẹn ni ko ṣe ṣe.

WO IYOKU NI OJU EWE KEJE

BERE OJULOWO EGBOGI AWON FARANSE
TI A NPE NI :-

"UROXAL"

Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney - Bladder fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu Ehin didun eri ile itọ itọ-jijo enia, itọ riru, rukuruku Pipọn tabi riruo, lakuregbe, Ibara di wiwo, orunkun, ọwọ, ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju, aiko le gbe ara konkon tabi kiakia, d daji loru nigbakugba, ati orisirisi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kia kia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ ko si ni Ilu Naijiria nitorina ṣora ki awọn eleru tabi awọn oni rọbirọbi ma ta orisi omiran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba rara o!

Owo rẹ jẹ Ṣile Mẹfa abọ 6/6d owo ọkọ sile meji abọ (2/6d)

Bere Egbogi yi ni Ṣọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-



**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ATI NI AWON ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.

ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES.
APATA AIYERAIYE STREET, ADEỌYỌ IBADAN

## Alo o! Alo

Lati Qwọ: Ọmọ Ẹgbẹ Imọ'ẹ Aiye No. 141

A ni ki o ṣiṣẹ, o ṣiṣẹ, nigbati a ni ki o sinmi, onsọkun Kini nje bẹ? Kanrinkan ti a fi nwẹ. (2) Oruku bi Igba ọmọ, gbogbo wọn jẹ ajẹ. Kini njẹ bẹ? Ata wẹwẹ

### O BẸRẸ LATI OJU EWE KẸTA

Mẹta yi na ni. Akọkọ ibikibi ti wọn ba wa, wọn ko fe ṣe ọmọ ẹhin rara, ayafi asiwaju, bẹ ni ibi ti Ọlọrun ba ni ki a mọ, ibẹ na ni a o de, a ko si ni tayọ ibẹ rara Ekeji nipe Ijoko gbogbo N. P. C. Ilẹ Igbomina nilu Eko ti a nṣe ni 19 Ijaye Street l'Eko. Alhaji Ọjọmu ni Alaga wa, nitoripe o jẹ Imọle, wọn ko fẹ gba fun. Ẹkẹta ni pe Ijoko Ajassẹpo eyiti Alhaji Gbadamọsi Ijaya ti ilu Ọffa tun jẹ a l a g a, on na tun jẹ Musulumi, wọn wa gbagbe pe a ki fi ti ẹsin ṣe Oṣeiu, ti ko ba jẹ bẹni mo fẹ ki ẹ ṣe iranti pe Ologbe Ọlọla Alhaji Akọshile lo gbe Ẹgbẹ N. P. C. de Ilu Oro, nitoripe o jẹ Musulumi, ni wọn ṣe korira rẹ, wọn ko gba fun, a dibo (Vote) fun Ologbe wa yi, wọn ko jẹ ko wọle, ni ọjọ ti a gbọ abayọri Ibo ti a di fun Ologbe yi, wọn na Baba Ologbe na titi di bi mo ti nkọwe yi Ile Ologbe na ni awa N. P. C. Ekumẹsẹsan Oro, ti nṣe ipade Ẹgbẹ wa yi, wọn ko si fẹ wọle na lọsẹ Ipade, wọn wa korira rẹ dopin nitoripe o jẹ Imale.

Wọn si gbagbe pe oludasilẹ Ẹgbẹ N. P. C. jakejado Ilẹ Naijiria ni. Ọlọla Alhaji Amọdu Bellow Musulumi ni, wọn si tun gbagbe pe Ọ l ọ l a wa Minister Ọgbẹni M. A. Ọlarewaju kiṣe Imale, bẹni on nikan ni awa ọmọ Ilẹ Igbomina nfi Sogo loni.

BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TỌNIKI TITUN TI O ṢẸṢẸ DE TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMIREN" TONIKI

EGBOGI AJEBIDAN FUN AGBALAGBA ỌKUNRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani ti nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ. Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yẹn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn Ogbologbo Dọkita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mọ daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ. Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe, ti o ko ba le jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de ọkọn lọsan tabi loru, bi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara to E-emi (breath) inu ko ba gunlẹ daradara to nitoripe arẹ tabi wahala ṣiṣe to "NJE" fun awọn ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun lọ si oke de adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di Ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kọnkọn nigbakugba "Arẹ" nigbakugba yio salọ patapata pẹlu.

Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
4, WAKEMAN STREET, YABA. PHONE: 22878

## Idahun si oro Ogbeni wa ti o pe ara re ni Dele Atolagbe

LATI ỌWỌ:- J. A. ỌLABAMIJI (ORO)
No. 168, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Inu mi yio dun bi O l ọ t u bale gbami laye lati ba Ọgbẹni Dele Atọlagbe sọrọ diẹ. nipa ọrọ ti o sọ jade ninu Iwe Irohin Imọlẹ Oloyin mọmọ, (4 Sept. 10 Sept.) O sọ wipe awọn Onigbagbọ O r o, korira awa Onimọle Oro. Awọn Agbalagba lo ma npa lowe pe: "Ẹru kan lo nmu ni bu Igba Ẹru." Iwọ Atọlagbe nikan na ni o sọrọ nipa Iyawo, ko si Ile Onigbagbọ kan ti o de, ti o o tọrọ ọmọ wọn, ti wọn ko fun ọ ti o ba si tọrọ ọmọ ẹnikẹni ti ko ba fun ẹ, o yẹ ki o daruko rẹ, o wa dun mi pupọ pe, bi gbogbo aiye ti nwa aye lati de ipo ti Azikiwe tabi Awolọwọ ati awọn bebọ lọ, ọrọ Iyawo lo wa ndun ẹ lọkan.

Ti o ba tọrọ ọmọ Onigbagbọ ti wọn ko fun ẹ, o ye ki o ronu dada lati ri pe, o kọ iru ọrọ yi jade ninu iwe Irohin Imọlẹ. Ki o mọ w i p e ati ba orukọ gbogbo awa Imọle jẹ ni yẹn. Wọn a ma s ọ p e ọrọ Iyawo lo ndun awọn Onimọle lọ kan gbogbo ẹgbẹ ẹ njẹ mayẹ loye onsa pe ẹgbẹ; Ti ọrọ ba ndun ẹ, o yẹ ki o da esi Iwe yi pa da ni ọsẹ ti o mbọ pẹlu, ati orukọ Ile rẹ ni Oro.

Jọwọ Ọgbẹni J. A. Ọlabamiji ma ṣe tun dahun iru ọrọ bayi mọ, nitoripe awa ko fẹ iru idahun bayi fun ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ. Ti o ba ni ọrọ lati sọ sinu Iwe yi a ko ni ki ma sọ o.

AKỌWE AGBA

## Okunrin yi ni Alejo nla to wa be Ilu Eko wo



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni ọkan ninu awọn ijoye Ọmọba ilu Gẹsi, orukọ oye rẹ njẹ Duke of Devonshire M. G. On ni a gbọ pe o wa bẹ ilẹ yi wo fun akọkọ Igba diẹ. Ogunlẹ silẹ yi lọjọ 15th oṣu yi. Ilu Ghana lo kọkọ bẹwo ko to de silu Eko.

Gbara ti o de o rin gbogbo ipinlẹ Naigiria kari, ki o to wa wa fi di joko si Eko lati ibẹ ni yio ti pada silu rẹ lọjọ kẹrin oṣu kẹwa ọdun yi (4/10/61).

# Petepete T'ana ni popa

Lati Ọwọ:- DELE ATỌLAGBE

ẸNYIN OBINRIN, Ẹ FI ETI SILẸ GBỌ ỌRỌ MI

Orin kan wa ti a ma nkọ ni ede Y o r u b a bayi pe:- Ọmọde ẹ ṣe Igbọran o, ohun rere ni o, ẹ ma ṣe eti kunkun, Igbọran ere nla ni o lẹhin ọla." Ṣugbọn nisisiyi, ori awọn agbalagba ni mo fẹ kọ orin temi fun "Agbalagba ẹ ṣe Igbọran o, ohun rere ni o, ẹ ma ṣe eti kunkun, Igbọran ere nla ni o lẹhin ọla"

O ṣe nigbakan, obinrin kan wa ti orukọ rẹ njẹ Kigbọran, Kigbọran jẹ obinrin kan ti o jẹ alagidi enia, ifẹ inu rẹ ni ma ṣe nigbagbogbo. Ọkọ rẹ kilọ fun, ṣugbọn ko gbọ, o di ni ọjọ kan Kigbọran gbe ikoko omi, o kori si odo lati lọ pọn omi lọsan gangan, awọn ara i l e rẹ wi fun bayi pe, e ṣe ti o fi nlọ si odo lọsan gangan yi; Jẹki o di irọlẹ, ṣugbọn Kigbọran ko gba si wọn lẹnu, o si fesi pe, Isisiyi ni ngo pada de

Ki a ma fa ọrọ na gun lọ titi, Kigbọran kori sodo, nigbati o de odo, o ba Iya Arugbo kan to da aṣọ bori o si bẹ pe ki o jọwọ ba on gba ọmọ ọwọ on dani ki on fi sare pọn omi lodo, Kigbọran ti ko ri oju Iya Arugbo yi tẹlẹ, ti ko si mọ iru enia to jẹ, o ba gbe ọmọ ọwọ rẹ fun Iya Arugbo na, o si lọ sodo lati pọn omi bi ọmọ Kigbọran ti de ọwọ Iya Arugbo yi ni onitọhun ba bẹrẹ si jẹ ọmọ na bi o n j ẹ titi o fi jẹ ọmọ na ku egungun lasan. Niwọngbati o ti pe aṣọ ni Iya Arugbo yi da bori, ko jẹki K i g b ọ r a n mọ o h u n ti o nṣẹlẹ labẹ aṣọ.

Kigbọran pọn omi tan, o si gun oke o d o pe ki on gba ọmọ on lọwọ Iya Arugbo na, o si sọrọ pe Iya Arugbo o ṣe pupọ o, j ọ w ọ ba mi gbe ọmọ mi. Bẹni Iya Arugbo ba nkọrin labẹ aṣọ bayi pe. Mo gbe de o, jẹjẹ ni mo joko, Iwọ lo gbe ọmọ fun mi, mo ba fi ọmọ na panu,, mo fi ọwọ rẹ panu, mo fi ẹ s ẹ rẹ panu, mo fi ori rẹ panu. Bi Iwọ Iya papa ko ba sọra rẹ, ngo fi ọ panu pẹlu. Bi Kigbọran ti gbọ o r i n yi ni o ba si aṣọ loju Iya Arugbo, o fi igbe ta pe, mo gbe o, mo ku lo ni o, mo ṣe de bẹ, kini ngo ti wi bi mo ba dele loni.?

Nigbati o si ti jẹ pe gbogbo enia lo ti kilọ fun Kigbọran ki o to jade nile. Itiju yi ko jẹki o le pada sile, bayi ni o ba Pokunso ninu I g b o ti o si pa ara rẹ. Iwọ Obinrin alaigbọran ewo loṣe.?

# Iya ngun ori Esin, Omo ngun ori enia



Ọmọde ti a nwo ti Obinrin kan gbe dani ninu aworan yi ni, ọmọ ti Elisabeth Ọba Gẹsi bi gbẹhin.

Nigbati Margaret ati ọkọ rẹ ngbatẹgun ọlọfẹ ara lọ si Idalẹ, lo sọ fun Ọba wipe on fẹ gbe ọmọ na gbatẹgun lọ, Ọba si gba fun.

Ọmọ na ni a nwo ninu aworan yi nigbati o tiajo de, ti Olutọju rẹ ngbe lọ si ọdọ Iya rẹ. Iya rẹ ngun Ẹṣin, wo bi on na ti ngun enia.

,'EYAGO FUN EJO TI APA TI A KO GE LORI"

# Ijinle imoran fun Omo ile Igbomina Offa, ati Ekiti.

Lati Ọwọ:- Ẹni Ọwọ Ọmọ ARIDẸGBAJU ORO.

Ẹnyin Ọmọ ilẹ Igbomina, Ọffa, ati Ekiti, Mokiyin pupọ lọmọde, lagbalagba, lọkurin ati lobirin, gbogbo yin ni mo ki patapata, Ẹku atijọ Oluwa, Olodnmare ko ni ba orilẹ ede wajẹ, ki Ọlọrun kio wo Ọla Anọbi wa Mohamad (Peace be on to Him), kio si wo Ọla A n ọ b i Yisa ti se Jesu, kio ti Olododo lẹhin, kio mase dọju ti Olododo lailai

Ẹjọwọ ẹkiye sarayin ekiyesi Ejọ ti apa ti ako ge lori, Orisiṣi ẹgbẹ oselu lowa nilẹ Igbomina lode oni, Ẹgbẹ olomi wa ẹgbẹ Igbomina parapọ wa, Awọn kan tun wa ti wọn sope awọn da Ẹgbẹ ọdọ silẹ larin Ilu Ọtun Oro ekiye si awọn enia wọọyi dada, mofẹ kiẹ mọwipe inu ẹgbẹ Igbomina parapọ ni wọn ti kuro wọn wa da ẹgbẹ ọdọ silẹ Irọ ni wọn npa kaka kio san fun Iya Ajẹ, pipele lonpele, ti nbi Obirin kun Obirin Eiyẹ wa nyilu ẹ yẹ, ẹmase da wọn lohun rara, Irọ ni ẹ npa asoju ẹgbẹ Igbomina parapọ na ni wọn. Ibasepe ẹgbẹ N. P. C. ni wọn fẹ ṣe, kini se ti wọn kọlọwọ ẹgbẹ na ni ilu wọn, ẹgbẹ N. P. C. wa ni gbogbo ilẹ Oro patapata won ko wọ ẹgbẹ na nibẹ wọn ko si wọ ẹgbẹ N. P.C. ti gbogbo Igbomana, ti ibujoko wọn wa L'ajasẹpo, ako si ri wọn ni 19 Ijaye Street, l'oko ni'le Ọlọla wa Alhaji Ọjọmu, ẹkoripe irọ ni wọn npa.

Kiẹ sc iranti pe, motl ligbakan sọfunyin pe ilu kan wa nilẹ Igbomina ti wọn kofẹ ilọsiwaju ilu miran ju ilu wọn ni kan lọ, wọn ko fẹ kio dara fun ilu miran ayafi ti wọn nikansoso meni Adan ni wọn koseku wọn koṣeiye, wọn kosifi'ra pamọ.

Ẹiyẹ ati Ẹranko wa bẹrẹ sija, nigbati adan ripe ẹiyẹ lofẹ ṣegun olo pẹlu wọn, oni ẹ yẹ ni on se oniẹkori iyẹ apa on ni, awọn ẹ yẹ sigba fun adan pe ẹ'yẹ nlae, ṣugbọn ni idakeji awọn ẹranko wa ṣẹgun adan tun lọba ẹranko pe eranko ni on ẹkori eti on ati bi on ti ni ehin lẹnu ni, Ilu na nrun larin ilẹ Igbomina nisisiyi, ṣugbọn nigbati Ọlọrun bafi ilu na han wa dada nipa wa ibajẹ, ifẹ tara ẹni nikan gbogbo awa ilẹ Igbomina, yio wa mọpe ilu na ni koti jẹ ki ilẹ Igbomina ni ilọsiwaju lati Ọjọ wa.

Mo wa bẹ ẹnikẹni ni nilẹ Igbomina, Ọffa, ati Ekiti, ẹgbẹ Olododo ni ẹgbẹ N. P. C. ẹgbẹ ti o korira Okunkun ni ẹgbẹ Olomi, ẹgbẹ ti bani koya ti bani kọ ẹgbin ni ẹgbẹ N. P. C. ẹwa se ẹgbẹ N. P. C. papa julọ ti Iwọ bakuro ninu ẹgbẹ Igbomina parapọ, ẹwa se ẹgbẹ Olomi ẹma se da ọdọ silẹ ako nigba iyẹn lọwọ yin, ekuro ninu ẹgbe ọdọ.

Nkan pataki meta ni awọn ara ọtun Oro niti wọn kofi fe faramọ egbe Olomi tele mofe ki eyin Igbomina, Offa, Ekiti sakiyesi nkan mẹta yi dada e o ripe nkan

WO IYOKU NI OJU EWE KẸFA

# Ajegboro dagba Nki Nyin o!

MO DE, EMI Ọkunrin wọkọwẹkọ, omi tutu ti jo eni mọti. Mo tun gbe de onigege pagan, mo ju tọse tokọja nu, mo nọwọ mu omiran. Emi ni ọmọ abi re ki rin oru, Jakumọ ki rin ọsan, mo tun gbe de oloyin mọmọ.

YE! ẸNYIN ABIYAMỌ KINI ELEYI O?
AṢỌ NI, TABI KINLA

Ṣe gbogbo ẹnyin Ọnkawe Irohin Imọlẹ mọ pe, oju ẹniti o nba nrin irin kurin, oju rẹ a si ma ri iri kuri, on lo difa fun Ajẹgboro dagba lọsẹ tokọja nigbati o nlọ lori kẹkẹ rẹ ni igboro ilu Eko. Ẹ bere nkan ri mo ti. Kini o ri? Bi mo ti rin ti mo si ngbadun ẹmi mi pẹlu atẹgun to dara ni opopo kan leko ni ri ọmọbinrin kan to yọ lọkọn, bi mo si ti ri lọkọn, ẹru bami, mo ro pe were ni, Kilo fa? Nitori ẹwu to wọ o dẹru ba ni pupọ, nigbati o sun mọ tosi mi ni mo wa ri pe Ọmọge to dara ni a mọ ẹwu to wọ yi ko dara ko yẹ ọmọ luwabi

O dun mi pe emi ko gbe ohun ti nwọn fi ya aworan enia dani (Camera) Emi ko ba ya ẹwu na fun yin, Ẹwu na tun yatọ si bonfo, gbogbo enia ti o ri aṣọ na lọjọ na lo ki gbe pe, e wo leyi o! ti wọn si nsọ pe iru aṣọ bayi ko dara bẹni iya rẹ wa nile to fi lo aṣọ buruku yi jade.

Mo pe gbogbo ẹnyin Ọlọmoge (Ladies) to nlo iru aṣọ buruku bayi, ko dara. ẹ ye lo aṣọ ti ẹ o wọ tan ti gbogbo enia to ba pade yin yio ma bu yin, tabi aṣọ ti ko si alubarika nibẹ pada julọ ẹnyin ọmọ Imale, aṣọ ti o jẹ pe ti ẹ ba wọ tan gbogbo rẹ a wa ta gẹgẹ lara yin, awọn aṣọ buruku ba wọn yi na lo nfa iṣe kuṣe ti awọn ọmọ wa nṣe loni. Ẹ lọ fi Iru aṣọ buru bayi ṣilẹ.

Ẹnyin Abiyamọ ati Alagbatọ, ẹ jọwọ mo bẹ yin ẹ ma ma gba awọn ọmọ yin laye ma lo iru awọn aṣọ buru ba wọn yẹn, gẹgẹbi bonfo, site, ayafi eyiti ẹ ba ri pe o dara.

Ti a ba tilẹ sọ pe, a nko aṣa awọn Oyinbo, o yẹ ki a mọ iru eyiti a ma ko, bi a ba si ni a nfẹ ma lo iru aṣọ wọn eyiti o ba dara ninu rẹ lo yẹ ki a ma lo, kiṣe gbogbo iru aṣọ wọn, nitori awọ wọn yatọ si ti wa.

Ẹnyin Ọlọmoge (Ladies) mo bẹ yin pupọ, ẹ lọ fi awọn aṣọ buruku ba wọnyi silẹ, ẹ ma lo aṣọ oyinbo to ba dara ti o si ni alubarika, ti a ba tilẹ wo awọn to nlo irufẹ aṣọ bayi ọmọ ile ẹko lo pọ ninu wọn, aṣo buruku yi na jo njẹ ki awọn ọmọdekunrin ma le yin kiri to ba wa di pe oyun de wọn yio fẹ sẹ fẹ.

Nitorina mo bẹ yin ẹ lọ fi iru aṣọ epe bayi silẹ. Iwọ Obi ti o ri ọmọ rẹ to nlo, ti o si nwo niran ti o ko si sọ fun, o di ọwọ rẹ, mọ daju pe iwọ ni wọn yio ma fi epe ranṣẹ si ni ile, nitorina ẹ ye ma ma gba awọn ọmọ yin laye lati ma lo iru awọn aṣọ epe bayi ti ko si Alubarika nibẹ.

Lọsẹ to mbọ lẹgbara Oduduwa ẹ o tun ma gbadun mi siwaju si. Ẹ toju kọbọ meji yin silẹ. A o pade layọ.


## Akiyesi pataki

**Sengovan Tablets! Sengovan Tablets!!**

(EXTRA STRONG FOR AGED MEN.)

SENGOVAN Tablets: Jẹ ajidewe fun awọn agbalagba ati Ilera gẹgẹbi ọmọkunrin.

SENGOVAN: Jẹ ọkan pataki ti a ṣe iwadi ni ilu Okere ni ilẹ Jamani lọwọ ọkan ninu awọn Ọjọgbọn Oniṣegun Arẹmọ ti ilu Western Germany. Fun arẹ ara ẹniti ọjọ ori rẹ to Ogoji si Ọgorin ọdun (40: 80. years.)

SENGOVAN:- Jẹ ogun ti o ti wa lọjọ pipẹ fun anfani awọn Agbalagba Ilu Jamani, ki ato ṣe amuwa rẹ si ilu Naijiria. Ajẹ bi idan ni ogun yi Irohin ko to afojuba.

Bere. a o ri lọwọ awọn Oniṣegun (Doctors) Naijiria tabi lọwọ Alagba wa Messers HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES. 26, BISHOP STREET. LAGOS PHONE. 23745. DIRECTION: 1 to 2 Pills is sufficient for your constitution, if so, do not take more pills at one time. SENGOVAN IS FOR YOU.



## MOGBAYI BABY MIXTURE
OLURANLOWO FUN AWỌN ABIYAMỌ

MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ti a se ni ase pe fun awọn Ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin pẹlu idaniloju fun Awọn iṣe ribi ribi ti o ti nse.

MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara fun igbona, ikọ, otutu A i p e r i, Osi inu Ọmọde, jedijedi, kokoro ori Ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ọmọde ko ma nsun fọnfọn o nmu ki ehin hihu jẹ irọ run fun awọn omode osi njẹki awọn omode tobi, osi nmu won dan ni awo. Ẹnyin Abiyamọ, eku afojuba egbogi yi. Aran yin letipe MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi ti ko se mani fun awon omode I j a f a r a lewu pupo, tete lo ra tire ni le itaja Egbogi towa ni Adugbo re.




Igo kekere re jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d

**LILO RE:- Sibi kekere lemeta lojumo**

*Wholesale Distributors*
A. K. KARIMU ANJOLA & BROS.

6, Balogun Street, West 34, Docemo Street
Lagos Nigeria Lagos
Phone 22515 Phone 24247


## Ero isoro ti awon Alaisan yio ma fi soro



Ẹniti o duro ninu aworan ti a nwo yi ni ọkan ninu awọn Olutọju Alaisan nigbati o ndan Ẹrọisọrọ ti awọn Alamọdi fi nsọrọ wo. Eyiti nwọn ṣe fun awọn ti ara rẹ ko le lati ma fi sọrọ.


### Ogun Itaja

**E ma polowo oja nyin sinu iwe Irohin I m o l e nigbagbogbo**

# ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

## Amulumola ede Yoruba ko dara

Lati Ọwọ RASHED ESUNAIKE. OMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE No 206.

Mo kiyin lọkunrin lobirin lomọde ati lagba, Ajinde ara yio ma jẹ mo ki ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ ati akọwe agba ino mi si dun nigbati mo gbọ pe iwe Irohin Imọlẹ di oju ewe mejọ, mo ki Olotu ati awọn oṣ ṣẹ wipe ẹku ori re o, Ọlọrun yio ran yin lọwọ ASE.

Ẹsio ọrọ mi ni yi, nipa "Ede Ilẹ wa" ojẹ ohun ti o ya mi lẹnu lati ri wipe awa ọmọ Bibi Yoruba ni atun le ma se Iru eyi, nipa ki asọ ede ilẹ Baba wa nu,ki asi ma tun sọ Ede Elede eyi ha dara bi, ṣugbọn mofẹ ki ọmọ ile Yoruba mọ dajudaju wipe awọn Oyinbo papa fẹ lati ko ede ti wa wọn si mo dajudaju wipe Ede ti odara ni nse, ṣugbọn mo se akiyesi ni ọsẹ ti okaja ni opopọ Yaba ni tosi Bus Stop nigbati emi ati Ọrẹ mi duro ti osi nba sọrọ mo ri awọn Ọmọde kurin meji kan ti wọn sọrọ ni biti wọn sọrọ ni ọkan sọpe njẹ ojẹ mọ wipe Iwill uot come to School again ni oti sọ Yoruba mọ Oyinbo.

Eyi ara mo fẹ ki emope bi enia ba maje Ọsaka ki ojẹ Ọsaka, ti enia ba si majẹ osoko ki o jẹ osoko. Iru iwa bayi ko dara rara lati ma sọ ede leede mọ ẹni. Ṣe bi ati gba Omiṇira na e se ti ama fi tun sọ Ede elede ti akọ ma sẹ ti wa, ṣugbọn enyin ara mofe ki emo daju wipe ko bi si awọn Oyinbo ti lokọ ede Yoruba to ti wọn yio ta Ede Isẹdalẹ wọn danu Ẹgbo owe kan ti osọ bayi wipe:- Eti ibi isana kesi Ogun awọn Hausa ti o wa ni Ilẹ yi wọn kojẹ sọ wipe awọn yio sọ ede awọn nu nitoripe awọn ti gbọ Yoruba.

Ṣugbọn ohun ti koye wa ni pe, Eko ko mo bi Oluwa se pọn ede Yoruba le to, ẹwo ilu Oyinbo wọn ti nfẹ ma kọ Yoruba nibẹ wọ nyio si tun wa fun ni nibẹ pẹlu nitorina mo bẹ yin pupọ ẹmajẹ afi ọwọ Osi juwe ile Baba wa o, Lẹkan si mo ki gbogbo ẹnyin Ọnkawe Irohin Imọlẹ.

## O ha leto bi?

Lati Ọwọ:- MUKAILA ỌLANIYI. OMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE NO. 156.

Olotu/ Jẹwọ gba mi laye ninu iwe Irohin rẹ oloyinmọmọ lati lebere ibere mi yi lodo awon elegbe mi to jẹ ọmọ Egbe Imole Aiye Ibere na lo bayi Njẹ o ha to fun Obinrin lati ma kiri Alukurani kakiri Igboro. Mo dupe lowo Olotu fun aye ti e gba mi owo omo araiye ko nitẹ yin. Iwaju le o ma lo e ko ni lo ehin lailai. Amin.

## Agbe ile Yoruba lo be awon Oja Ile Gesi wo



Obinrin agbẹ kan, ati awọn ọkunrin agbẹ meji lati ipinlẹ Iwọ - orun lọ silu Oyinbo lati lọ wo awọn agutan ti awọn Gẹsi ni fun ti ta ni ọja wọn ti o wa ni Winford ni lu Oyinbo.

Eniti o se atọna awọn enia na ni Ọgbẹni Oloye A. O. Adeyi ti a nwo lọwọ osi ninu aworan Ivafin I. M. M. Oṣimosu ti Abẹokuta ati oloye T O. Awosika, nwọn nna agutan Oyinbo lati ma wa sin nilẹ wa nihin.

## ITAN IGBESI AIYE AWON ORE MEJI

Lati Ọwọ:- LASISI BABALỌLA
Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye No. 8.

Inu mi yio dun bi olotu ba gba mi laye ninu iwe rẹ oloyin lati le fi itan mi yi si awọn ẹlẹgbẹ mi leti, awọn ọrẹ meji kan wa, ekini njẹ Ọlatunji, ekeji si njẹ Ọlakunle, awọn meji jẹ ọrẹ timọ timọ, Nwọn a ma fun ra wọn ni mọrọn pẹlu awọn asi ma ba ara wọn jẹun, wọn ma sun pọ lọjọ miran, wọn si jijọ lọ si ode

Ṣugbọn Ọlakunle nma hu iwa ti kotọ si Ọlatunji nigbati wọn ba de ile Ọlatunji awọn a jẹun wọn ayo daradara a jẹti ni wọn yio fionjẹ ra ṣe. Ikun wọn yio si ri rogodo, ṣugbọn nigbati o ba kan Ọlakunle idaji o onjẹ ti Iya rẹ gbe fun ni o gbe silẹ, yio si tọju yoku titi Ọlatunji ma fi lọ sile rẹ, nigbati Ọlatnnji ba lọ s'le yio si lọ gbe onjẹ na yio jẹ.

## Alaga U. A. C. lo fun Isimi ni ilu Oba.

Ọgbẹni J. B. Davies, O. B. E. ẹniti iṣe alaga ti ẹgbẹ awọn Onişowo ti United Africa Company of Nigeria Ltd. yio lọ si Ilu Ọba fun oṣu mẹta ni ogunjọ oṣu yi fun Isimi. Ọgbẹni N W. I Kay lati ibi-iṣẹ U. A. C. ni Ilu Ọba ni yio dele de e.

Ọgbẹni Kay ki iṣe ajeji ni Ilẹ wa. O ti wa nihin ri fun ọdun mẹrinla lati 1930 titi di 1944; lẹhin igbana o lọ si Gold Coast ti a npe ni Ghana nisisiyi fun ọdun meji, o tun pada wa sihin ni 1946. Ni ọdun 1948 ni o pada si London lati ma bojuto ibi iṣẹ U. A. C. ti a npe ni Nigeria Department.

Ọgbẹni Kay pẹlu Iyawo rẹ li o de sihin nisisiyi, wọn yio si bẹ awọn agbegbe mẹta Ilẹ wa wo lakoko igbati wọn ba wa nihin.

AWỌN IWE KO ṢE MANI
IWE EGBOGI FUN ONIRURU IWOSAN;
IWE ADURA IṢẸGUN AWỌN AJẸ;
IWE IFA AGBỌN-NIREGUN. IWE ITUMỌ ALA PẸLU IWADI NKAN;
IWE LILO ATI AGBARA PSALMU:
IWE ADURA TETE DA MI LOHUN:
IWE ITAN ABALAIYE ATI TI IṢẸDALẸ

KỌWE FUN IWE-ITAJA:-
OLOTU BOX 104
EBUTE METTA, NIGERIA

# Oloye kan pe Gomina Iwo-Orun lejo si Kotu Abeokuta



Abẹokuta:- Ijoye kan ti nwọn npe ni Ọlọfin ti ilu Ilişan, ẹnit o şe aşe maşe si ijọba ti nwọn si ti rọ kuro ni Oye ni o şe iwe si Kotu Abẹokuta wipe ki Adajọ Ọgbẹni W. T. Charles jọwọ gba ọrọ ti on ro ki o si da on pada sori oye Ọba Ọlọfin ti ilu Ilişan ni agbegbe Ijẹbu (Ijẹbu Provice) Eyiti Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọlọla Adesọji Aderẹmi lowọ sinu rẹ.

Agbẹjọro fun Ọba na Ọgbẹni Olu Ayọọla ti o mbẹ ni ilu Ibadan sọ fun adajọ Ọgbẹni W. T. Charles wipe loju ti on, oa ri pe Gomina Iwọ Orun ko şe ẹtọ loju ti on, Orukọ Ọlọfin ti ilu Ilişan ti wọn l'kuro loye ni Ọba Ishemaei Ọbafẹmi Green Adebọ.

## Ma a ka iwe Irohin Imole nigbagbogbo


GBANGBA DEKUN!! KEDERE BEWO!!!




**PORAL**

OLUBORI EGBOGI "IKỌ"

Bi Amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu fun nkọn bi ọdun kan tabi jubẹ lọ, awọn egbogi rọbi-rọbi ko le şe iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ şe Ofo mọ.
Bere fun egbogi awọn ara Ilu Faranse ti wọn npe ni. "PORAL" ojulowo haunhaun, atamatase egbogi fun Ikọ here, Ikọ tutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaiya, Ikọ lile, Ikọ-ti o ma mu enia tu kẹlẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun" wa (Lungs) tabi ti o ma nmu enia ru pẹlu. Bi o ba dan Igo kan egbogi PORAL yi wo, Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia, Igbaaiya tabi ọna-ọfun rẹ ti o ma nho yio duro, "IKỌ" rẹ yio si san patapata, iwọ yio ma jẹun daradara iwọ o si sun fọnfọn pẹlu Alafia de.
Bere egbogi yi ni Şọbu:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ATI NI AWON ŞOBU IBADAN:-
IŞẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.
ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES.
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN.


### O BẸRẸ LATI OJU EWE KEJI

Awọn Ọlọpa Ibilẹ ti o mbẹ ni Iwọ Orun sọ pe nigbo gbo igbati nwọn fi nşe atako si awọn Ọlọpa Ibilẹ Iwọ orun, nwọn ko tako awọn Ọlọpa ibilẹ ti Oke Ọya ro pe awọn Ọlọpa Ibilẹ ti Ipinlẹ Iwọ orun jẹ dọgba dọ gba pẹlu ti awọn Hausa.

Ijọba sọrọ pupọ lori ofin pẹlu aşẹ nilẹ wa, nwọn si ba awọn aşiwaju mejeji na sọ akọ ọrọ, nwọn si pari edekoyede to wa larin Olope S. L. Akintọla pẹlu Dr. Ọpara, bẹni ọrọ na ba mupo.


**For all your Printing Requirements**

Invitations, Programmes, Hand Bills, Pamphlets, Advertising Material and all Commercial Jobbing

Send your Jobs to :-
MODUPE PRINTING PRESS.
16, Bamgbose Street, Lagos. Phone: 21985

**Where Quality Print, costs less.**



## Owo eni lafi ntun iwa eni se

Bi ailowo lọwọ ba nda ọ lamu, bi airọmọbi mba ọ lọkan jẹ, tabi airiṣẹṣe lo nyọ lẹnu, ọ tabi o tilẹ nṣẹẹ na owo iṣẹ na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn Ọmọrẹiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiyẹ rẹ bi gbogbo ọnu kọna.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njẹ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi oja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mba ọ lọkan jẹ ni gbogbo ẹjọ.

Mo daju wipe diẹdiẹ lo koko bere. Ki o si tun ona rẹ se. Kowe pẹlu Ṣile Mẹwa abọ (10/6) pẹlu Sitampu oni tọrọ (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunṣe adanwo na lọdọ:-

AWORAWỌ<br>
16, MỌLẸYẸ STREET<br>
P. O. BOX 166. YABA - NIGERIA


## PAYAL

Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi fun "Ipara" ti awọn ailera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu ode ara. Ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun nigbakugba. Alefọ. Egbo ẹsẹ oriṣiriṣi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ bi adajinọ gbo, Ekuṣẹ tabi Lapalapa, Ela, Ara sisu, Ako laarun lo oriṣiriṣi ẹrun "ARA" miran gbogbo.




Gbiyanju lati dan egbogi k o k o r o titun ti awọn aro Ilu Tatanbulu ṣe ti wọn npe "PAYAL" wo l a r i n ijọ mẹta iwọ na yio ma rohin rẹ fun awọn elomiran pẹ'u. Egbogi ipara yi ki ṣe awọn robirobi ti wọn nta kakiri ilu ni owo poku. Ojulowo egbogi arun nta hanunhaun ti ko si ṣiṣẹ iye mẹji ninu rẹ eleyi si yatọ patapata si awọn egboremiti adimọwọ ti won nta kakiri Igboro ati ni agbe reko gbogbo pẹlu. Oniṣi meji rẹ lowa, Kekere ati Nla.

Bere Egbogi Ajẹbina PAYAL yi ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**<br>
**8, Palmchurch Street Lagos,**<br>
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-<br>
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.

ADEFỌGUN PATENT MEDICINE STORES<br>
APATA AIYERAIYE STREET, ADEOYỌ IBADAN



SPECIAL PAGES FOR 1ST ANNIVERSARY OF INDEPEDENCE OF NIGERIA

On request of our readers, this journal will be publishing a pecial pages which will be on sale through out Nigeria on the 2nd of October for the 1st anniversary of Independence of Nigeria.

Traders, Mercantiles, and personalities who like to book or rates in the special Issue, Should Contact the:-

ADVERTISEMENT MANAGER<br>
16. Bamgbose Street, Lagos Phone: 21735.



FUN OWO IROHIN IMỌLẸ ỌDUN KAN<br>
EKO:- Ṣile Mẹjọ ati Kọbọ Mẹjọ (8/8d)<br>
Ilu miran ni Naijiria ati Oke Okun:-<br>
Ṣile mejila ati Kọbọ Mẹfa (12/6d)


## Ye Irawo re wo!

Iwọnyi ni awọn ohun ti yio ṣẹlẹ si Olukaluku enia gẹgẹ bi irawọ ọjọ ibi rẹ ti wi:

July 23 - Aug. 22 (Leo) Ohun anfani kan yio ṣẹlẹ si ọ ninu ọsẹ yi. Iwọ yio gbadun aṣalẹ ọjọ kan ninu ọsẹ yi.

Aug. 23 - Sept. 22 (Virgo) Ṣọra lọsẹ yi ki o ma ba ṣe wahala lori asan.

Sept. 23 - Oct. 23 (Libro) Maṣe jẹki ọrọ ile rẹ pa ọ laiya, nṣe ni ki o gbeti si ẹgbẹ kan, nitori ohun ti o mbọ wa ba ọ ni rere ju gbogbo rẹ lọ.

Oct. 23 Nov. 22 (Scorpio) Ṣọ ara rẹ lọsẹ yi maṣe ja ma si ṣe bu enia. Iyẹn lo dara fun ọ.

Nov. 22 - Dec. 22. (Sagittarius) Tun bọ fi ara mọ awọn gbajumọ ki aiye ba le dara fun ọ.

Dec 23 - Jan. 20 (Capricon) Iwa jẹjẹ ni awọn Obi rẹ fẹ eyi ni yio dara ti yio si dumọ awọn ọrẹ rẹ.

Jan. 23 - Feb. 19. (Aquarius) Maṣe jẹki iṣoro di ọ lọwọ ohunkohun ti o ba de, nṣe ni kio duro bi ọkunrin.

Feb. 20. - Mar. 20. (Pisces) Gbogbo ero rẹ lo pe, ti o si dara, iwọ yio si jẹ anfani ọrẹ kan, kio si tọju owo piẹ to mbẹ lọwọ rẹ.

Mar. 21 - Apl. 20. (Aries) Owo kan ti o ti nreti lati gba yio pẹ diẹ ki o to ri gba, ọrọ atijọ kan yio ruyọ ti yio si mu owo na pẹ diẹ.

Apl. 21. - May. 22 (Taurus) Iwọ yio lọ si ipade kan ninu ọsẹ yi, ọrọ ti ẹ o sọ nibẹ yio ṣe ọ ni afani pupọ.

May 23 - June 21 (Gemini) Ohun kanti o ti ni ero pe ko le ṣeṣe mọ, yio di irọrun fun ọ, ayọ aṣalẹ ọjọ na yio pọ

June 22 - July 22 (Cancer) Akoko ti o ti lero lati ṣe nkan rere yio yẹ.

## Obinrin kan ro Igbesi aiye re pin, ofi ada ge ona ofun re.

IDANRE:- Obinrin gbajugbaja kan ti gbogbo enia mo, ti nwọn si npe ni Iyafin Ogunrinọla ti iṣẹ iyawo Ọgbẹni kan ti nwọn npe ni Akinmọlaju. A ko mọ ohun ti o ṣe obinrin na ki o to ro gbogbo igbesi ọjọ aiye rẹ pin.

Agbọ wipe obinrin na lọ sinu ile, o fa obẹ ọkọ rẹ yọ ko tilẹ ronu wipe efun ni eyiyi tabi edi, ṣugbọn o fi obẹ na ja ara re ni gogongo

Nigbati ọbẹ na jo lo ba binu sọ ọbẹ nu awọn aladugbo gbọ igbe rẹ nwọn rọ wọ ile were awọn Ọ l ọ p a ti gbọ, nwọn wa gbe obinrin na lọ sile alaisan Awọn ọlọpa ranṣẹ pe ọkọ rẹ lati se itose oro lodo rẹ.

Ọkọ rẹ ko ri ohun kan so, obinrin na Ogunrino'a koiti le so ọrọ kan fun aiye gbọ.


## Ibanuje Tabi Ironu re de opin! Alafia ati Ayo de!

BERE EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE NI

**"CORSIVERA"**

Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatese Egbogi ti ase ni patiki fun:-<br>
"ARỌN KINIṢA TABI ARỌN LATỌNLATỌN" MEJI RẸ KOSI.

Bere lọdọ awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**<br>
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**<br>
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**